<u>**YUNIFÁSÍTÌ OMOLUWABI**</u>

# ẹ̀kọ́ Alúgórídímù

**A.AKIM**

## Alúgórídímù

Nígbà tí a bá fẹ́ kọ alugoridimu, ìgbésẹ̀ mẹ́ta ni a máa ń gbé.

**I <u>Àwọn ìgbésẹ̀ mẹ́ta náà ni</u>**

1.1 ) **Ìgbésẹ̀ kìíní**

Ìgbésẹ̀ àkọ́kọ́ ni kí a ṣalàyé àwọn ohun ìṣẹda ti a fẹ́ lò ( Àwọn oníyípadà, iró , nọ́ńbà..)

1.2 ) **Ìgbésẹ̀ kejì**

A á tú ìṣòro wa sí wẹwẹ ni onà ìpele mélòó kan. Èyí ni yóò fún wa ni ìrọ̀run láti yanjú ìṣoro yìí.

<u>Àpẹẹrẹ</u>

: A fẹ́ ṣírò ( a + b )

tẹ a;
tẹ b;
c ← a+b
ìfihàn “c”; / ni orí ìbójú

1.3 **)** **Ìgbésẹ̀ Kẹ́ta**

Ìtẹ̀jáde abáyọ ìṣoro wa, kí olùmúlò lè rí í kà.

**II <u>Kí ni alugoridimu</u>**

**2.1 Ọ̀nà ti a fi ń lò alugoridimu**

Alugoridimu fẹ́ fi ara jọ ètò, àmọ́ kìí ṣe é ètò nítorí àwọn ètò ní àwọn ìtọ́sọ́nà ( kóòdù ) ti a ń lò fi kọ wọn.

Alugoridimu kò níí àwọn ìtọ́sọ́nà ( kóòdù ) kan pàtó ti a ń lò. Olùmúlò gan-an ni yóò kọ àwọn ìtọ́sọ́nà ( koóòdù ) láti fi ètò sí èrò rẹ, fi rí ọ̀nà àbáyọ fún ìṣòro rẹ.

2.2 **Báwo ni a ń kọ alugoridimu**

Ètò : orúkọ ètò náà

Oníyí: oníyípada1, oníyípada2 ... : ohun ìṣẹ̀dá

**Ìbẹ̀rẹ̀**

ìtọ́sọ́nà 1 ;

ìtọ́sọ́nà 2 ;

ìtọ́sọ́nà 3 ;

**òpin**

### 2.3 Àlàyé àwọn ohun ìṣẹ̀dá

#### 2.3.1 Àwọn ohun ìṣẹ̀dá ìpinlẹ̀

Àwọn èyí ti a ń lò fún àwọn ètò ìkópọ̀ ( C, C++, cobol, java...).

Àwọn ni ìwọ̀nyìí : iró, àsòpọ̀ iró, nọ́ńbà rere, nọ́ńbà gidi, alákómejì, atẹ́.

#### 2.3.2 iró

Àwọn wọ́nyìí ni àwọn iró fáwẹ́ẹ̀lì, kọ́ńsónáńtì, nọ́ńbà, àti àwọn omìíran, báítì ni àṣojú wọ́n, báítì kan jẹ́ iró kan.

#### 2.3.3 Àsópọ̀ iró

Àwọn àsópọ́ iró yìí ni máa ń ṣàpèjúwé ohun ìṣẹ̀dá ti a ń lò bíi

Àpẹrẹ ilé, ìlú, ìyá ...

#### 2.3.4 Alákóméjì

Àwọn oníyípàdà tí máa ní ojú méjì (“ojú” , “òdì” ) tàbí (“òdo”, “òótọ́”) tàbí pẹ̀lù àwọn nọ́ńbà (“0”, “1”).

#### 2.3.5 Nọ́ńbà

Àwọn wọ̀nyìí ni odò, nọ́ńbà òdi, nọ́ńbà rere ;

<u>Àpẹrẹ</u> :

Nọ́ńbà òdi : -1, -2, -3, -4, -5, .........

Nọ́ǹbà rere : 0, 1, 2, 3, 4, 5, ...........

**2.3.6 Nọ́ǹbà gidi rere**

Apẹrẹ 1.2, 25.412, 452.478 .....

**2.3.7 Nọ́ǹbà gidi òdi**

Apẹrẹ -1.2, -25.412, -452.478 .....

**2.3.8 Atẹ́**

Inú atẹ́ yìí ni a máa ń kó àwọn ohun ìṣẹ̀da ti ó jọ́ra wọn sí, ti a sì fún ni orúkọ kánna tí ó jẹ́ orúkọ atẹ́ ti a so mọ́ orúkọ àwọn atọ́ka nọ́mba.

oníyí orúkọ(b1 ,b2): nọ́ǹbà

**2.3.9 Ohun ìṣẹ̀da**

Àwọn ohun ìṣẹ̀da ni àwọn tí ìpinlẹ̀ pẹ́lù àwọn èyí ti a ṣẹ́da wọn pẹ́lù ti ìpinlẹ̀ yìí.

Ìṣẹ̀da orúkọ-ìṣẹ́da= (........, ........, ........ )

Àpẹẹrẹ

Ìṣẹ́da ọlùkọ= ( èya : Nọ́mba, orukoakoko : àsopọ̀, orukoidile: àsopọ̀ iró )

**3 Àwọn ìtọ́sọ̀nà ìpinlẹ̀**

**3.1 Ìtọ́sọ́nà fi sí**

Ìtọ́sọ́nà yìí ni a máa ń lo fi fi ìṣẹ́da sínú oníyípadà. Àmì ọ̀fà ni a mán ń lo fi kọ ìtọ́sọ́nà náà.

< oníyípadà > ← < ìṣẹ̀da >

Àpẹẹrẹ

a ← 3;

Oruko ← “ade”;

**3.2 Àwọn ìtọ́sọ́nà ìwọlé àti ti ìjáde**

### 3.2.1 Ìtọ́sọ́nà Ìwọlé

Ìtọ́sọ́nà Ìwọlé ohun ìṣẹ̀da ni a máa ń lò fi fi í  sínú ìranti ẹ̀rọ kọ̀ńpútà ( ẹ̀rọ ìtẹwé kọ̀ńpútà ) ni tẹ.  A á lò oníyípadà fi gbé ohun ìṣẹ̀da ti a tè pamọ.

tẹ  < ohun ìṣẹ̀dá >

Àpẹẹrẹ      tẹ a.

### 3.2.2  Ìtọ́sọ́nà Ìjáde

Ìtọ́sọ́nà Ìjáde ohun ìṣẹ̀da máa ń jẹ́ kí a kọ ọ́ sórí ìbójú kọ̀ńpúta kí olùmúlò lè rí í kà. Ìtọ́sọ́nà náà ni **ìfihan**

**ìfihan** < ohun ìṣẹ̀da >

Àlàyé àwọn oníyípadà

Kí a tó lo àwọn oníyípadà a ni láti yaǹnanan wọn , báyìí ni a ń ṣe é.

oníyí orúkọ-oníyípadà : ohun ìṣẹ̀dá

A lè kó àwọn oníyípadà kannáà pọ̀ sínú kíkójọ kan.

Àpẹẹrẹ

oníyí     i, j, k :  Nọ́mba

## 4 Àwọn ìtọ́sọ́nà ìṣiṣẹ́

Àwọn ìtọ́sọ́nà ìṣàkóso alugoridimu ètò ni a ń lo fi ṣé wọn.

### 4.1 Àwọn ìtọ́sọ́nà ìṣàkosó

Ìwádìí àwọn ọjọ́gbọ́n fi yé wa wi pé a lè kọ alugoridimu ètò pẹ́lù ìtọ́sọ́nà ìṣákóso mẹ́ta, a máa ń pè àwọn wọ̀nyìí ni ìtọ́sọ́nà ìpinlẹ̀ .

Àwọn mẹ́tẹ́ta ni :

- lẹ́sẹ̀sẹ̀
- Àtúntúnṣe
- Omìíran

#### 4.1.1 Ìtọ́sọ́nà ìṣàkóso lésẹ̀sẹ̀

Àwọn ìtọ́sọ́nà ìṣàkoóso yìí máa ń fún wa ni àǹfààní láti kọ àwọn ìtọ́sọ́nà sínú ìkójọ kannáà, a á kọ àkọ́kọ́ sẹ́yin èkejì, èkejì sẹ́yin ẹ́kẹta... bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ́ lọ.

Ìtọ́sọ́nà 1

Ìtọ́sọ́nà 2

Ìtọ́sọ́nà 3

................

#### 4.1.2 Ìtọ́sọ́nà ìṣàkóso omìíran

Àwọn ìtọ́sọnà ìṣàkóso wọ̀yìí ni a máa ń lò tí a bá fẹ́ lò ìtọ́sọ́nà kan tàbí omìíran. Májẹ̀mu ni máa tọ́ wa sọ́nà.

Báyìí ni a ń kọ wọn.

Ti ( májẹ̀mu = “òótọ” )

Ìtọ́sọ́nà 1

bkbrb

Ìtọ́sọ́nà 2

ÒpinTi


**bkbrb** : bí kò bá rí bẹ́ẹ̀.

Àwọn ìtọ́sọnà ìṣàkóso omìíràn mìí


**4.1.2.1 Kúkúru**

Ìtọ́sọ́nà ìṣàkóso yìí máa ń wò ó tí màjẹ̀mú bá jẹ́ “òótọ” tàbí “òdo”.

A máa ń kọ ọ́ báyìí




Tàbí




**4.1.2.2 Gbọ̀ọ́rọ**

Pínnu nínú

Tí májẹ̀mu 1 :

Tí májẹ̀mu 2 :

Tí májẹ̀mu 3 :

........................

Omìíràn

ÒpinPínnu

**4.2 Ìtọ́sọ́nà ìṣàkosó àtúntúnṣe**

Ìtọ́sọ́nà ìṣàkóso ètò yìí ni a máa ń lò fi tún àwọn ìṣe ṣe.

Májẹ̀mu ni ìtọ́sọ́nà àtúntúnṣe yìí máa ń lò fi mọ́ ti yóò bá da ìṣe dúro tàbí ti yóò bá máa ba á lọ.

Nígbà ti ẹ bá máa kọ alugoridimu yín, ẹ ró májẹ̀mu ti ẹ yóò lò bí kò bá jẹ́ bẹ́ẹ̀ ìṣe yín kò ni dúró títí ayérayé.

Àwọn ìṣàkóso àtúntúnṣe méjì ló wà:

- Àtúntúnṣe “ìjáde òkè”
- Àtúntúnṣe “ìjáde ìsàlẹ̀”

### 4.2.1 Ìtọ́sọ́nà ìṣàkosó àtúntúnṣe "ìjáde òkè"

Báyìí ni a ń kọ wọn

| |
|---|
| Nígbà Tí ( májẹ̀mu àtúntúnṣe ) = "òótọ̣"<br>Ìtọ́sọ́nà 1<br>Ìtọ́sọ́nà 2<br>...........<br>Oníyípadà " ìtọ́sọ́nà ìṣákóso "<br>Òpin Nígbà Tí |

### 4.3 Àtúntúnṣe "ìjáde ìsàlẹ̀"

Báyìí ni a ń kọ wọn

| |
|---|
| Túnṣe<br>Ìtọ́sọ́nà 1<br>Ìtọ́sọ́nà 2<br>...........<br>Oníyípadà " ìṣákóso "<br>Títí ( májẹ̀mu ìjáde ) = "òótọ̣" |

4.4 Ìtọ́sọ́nà ìṣàkóso Fún

A máa ń lò ìṣàkóso Fún nígbà ti a kò bá fẹ́ lò ìṣàkóso àtúntúnṣe.

Báyìí ni a ń kọ.

```
Fún    I  kúró ni d dé  f  ẹsẹ̀ p  Túnṣé
|
|         Ìtọ́sọ́nà
|         .............
|
ÒpinFún
```

Àdáṣe

Ìṣirò   1 + 2 + 3 + 4 + 5 + 6 pẹ̀lú kọ̀ńpútà.

ÈSÌ

Ètò : Àfikún àwọn nọ́mba

oníyí :  i,s,n : Nọ́mba

```
Ìbẹ̀rẹ̀
|
|          I ← 0
|          s ← 0
|        Nígbà Tí   ( i < 7 )  ṣe
|        |
|        |     s ← s + i
|        |     i ←  i + 1
|        |
|        Òpin Nígbà tí
|
|          ìfihan   " s "
|
Òpin
```